**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**ÌTUSÍLẸ̀ TO JÌNLẸ̀ (APÁ KẸ́TA)**

**OṢÙ KẸFÁ, ỌDÚN 2024**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Márkù 9

Ìjẹ́wọ́: Lúkù 4:18

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Mo fi ẹ̀jẹ̀ Jésù sórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Mo fa òbìrí ẹ̀jẹ̀ Jésù yí gbogbo dúkìá àti àwọn ohun-ìní mi ká, ní orúkọ Jésù.
7. Àpáta Ayérayé, fọ́ gbogbo gbòngbò àjẹ́ nínú ìpílẹ̀ mi sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ìjókò àjẹ́ tó n dá ayànmọ́ mi lóró, gba àrá iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo agbára àjẹ́ tó walẹ̀ jìn sínú ìpìlẹ̀ mí di ahoro, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ibi gíga ìwà ìkà tó walẹ̀ jìn sínú ìpìlẹ̀ mí di fífà lulẹ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ọkọ̀ ìrìnṣẹ̀ àwọn agbára àjẹ́ nínú ìran ìdílé mi, gba ìparun nípa iná, ní orúkọ Jésù.

12. Mo kó àwọn ibùkún mi kúrò nínú ilé ìfowópamọ́ sí àti yàrá agbára ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo gbólóhùn àti àránsí búburú, tí wọ́n ṣe lòdì sí ayànmọ́ mi, gba ìfagilé nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
14. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, tú ọkàn mi sílẹ̀ kúrò nínú gbogbo ìbọ̀dè, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo pàṣípàrọ̀ àjẹ́ fún áísìkí mi, gba ìfagilé nípa iná, ní orúkọ Jésù.
16. Mo yọ gbogbo ẹ̀yà àgọ́-ara mi kúrò lórí pẹpẹ àjẹ́ ìyówù, ní orúkọ Jésù.
17. Bàbá, jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù fagilé gbogbo ìfani-wẹgbẹ́ ibi, tí wọ́n ṣe lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
18. Mo fagilé gbogbo ilànà búburú tí wọ́n ṣe lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
19. Bàbá, jẹ́ kí gbogbo iṣòro nínú ayé mi, tí ó jẹyọ láti ipàṣẹ̀ pàṣípàrọ̀ búburú gba ọ̀nà àbáyọ atòkèwá oju-ẹṣẹ̀, ní orúkọ Jésù.
20. Bàbá, jẹ́ kí gbogbo ibùkún tí ọ̀tá ìdílé fi sínú àhámọ́ gba ìtúsílẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ìbọ̀dè tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí mi, mo mú ìdájọ́ Ọlọ́run lòdì sí ọ, ní orúkọ Jésù.
22. Mo gba ìdúróṣinṣin mi kúrò lọ́wọ́ àwọn àgbà ìkà ìdílé, ní orúkọ Jésù.
23. Bàbá, jẹ́ kí àrá Ọlọ́run ṣàwárí, kí ó sì tú ìtẹ́ àjẹ́ nínú ìdílé mi ká, ní orúkọ Jésù.
24. Mo pàṣẹ kí gbogbo pẹpẹ ibi tí wọ́n yàn lòdì sí ìràwọ̀ mi gbiná, ní orúkọ Jésù.
25. Gbogbo ọwọ ibi tí wọ́n gbìn sínú ìpìlẹ̀ mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo ìránṣẹ́ òkùnkùn tó n ṣiṣẹ́ ìránṣẹ́ lórí pẹpẹ búburú ìyówù láti fa ògo mi wálẹ̀, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.
27. Gbogbo ègún àìmọ̀dí tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayé mi, gba ìfagilé nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
28. Mo fi iná Ọlọ́run ṣe ìparun fún gbogbo ohun-ìjà ìjákulẹ̀ tó lòdì sí ayé mi, ní orúkọ Jésù.

29. Gbogbo pámpẹ́ tí àwọn ọ̀tá onílara dẹ fún mi, mú ẹni tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
30. Bàbá, jẹ́ kí ọgbọ́n àwọn àgbà ìkà di òpè, ní orúkọ Jésù.
31. Mo tú ọkàn mi sílẹ̀ kúrò nínú gbogbo ibọ̀dè àjẹ́, ní orúkọ Jésù.
32. Èyí ìyówù nínú àwọn ibùkún mi, tí àwọn àgbà ìkà fi ṣe òwò, padà tọ̀ mí wá, ní orúkọ Jésù.
33. Mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò nínú gbogbo ìdè májẹ̀mú àìmọ̀, ní orúkọ Jésù.
34. Gbogbo ọwọ́ ibi tí ó gbin irúgbìn búburú sínú ayé mi nípa ṣẹ̀ ìgbógun tì látojú àlá, gbẹ, kí o sì jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo ìfayà, èpè àti àránsí tí wọ́n ṣe lòdì sí mi, mo gbé ọ dè, mo sì kọ ẹ̀yìn rẹ lòdì sí ẹni tó ni ọ́, ní orúkọ Jésù.
36. Ẹ̀yà ara mi ìyówù, tí àwọn àjẹ́ ìdílé pín mọ́ ara wọn lọ́wọ́, mo gbà ọ́ padà, ní orúkọ Jésù.
37. Ẹ̀yà àgọ́-ara mi ìyówù tí wọ́n ti ṣe pàṣípàrọ̀ rẹ̀ fún ẹlòmíràn nípa ṣẹ̀ ìṣe àjẹ́, gba ìrọ́pò báyìí, ní orúkọ Jésù.
38. Mo gba áísìkí/ibùkún mi ìyówù tí àwọn àjẹ́ ìdílé ti pín mọ́ ara wọn lọ́wọ́, ní orúkọ Jésù.
39. Mo tú ọwọ́ àti ẹsẹ̀ mi sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ibọ̀dè tàbí ìdè àjẹ́, ní orúkọ Jésù.
40. Mo kọ gbogbo ìkórajọ̀pọ̀ tàbí àpéjọpọ̀ padà àwọn àjẹ́ ìdílé àti àjẹ́ abúlé, tí ó lòdì sí ayé mi, ní orúkọ Jésù.